*Ireti Eda…!*

**EPISODE 24**

**<u>Characters</u>**

*Bello*
*Abokede*
*Wosilat*
*Ajani*
*Lukman*
*Iyabo*

---

**Scene 1**
**Ilorin. Wosilat's residence!**

| | | |
|---|---|---|
| 1. | **SFX**: | **<u>KNOCK ON THE DOOR</u>** |
| 2. | **ABOKEDE**: | (**DISTRACTEDLY**) Yes? Ta ni yen? |
| 3. | **BELLO**: | (**OFF MIC**) Bello |
| 4. | **ABOKEDE**: | (**EXCITEDLY**) Ah, ife mi. Mo nbo. |
| 5. | **SFX**: | **<u>DOOR OPENS</u>** |
| 6. | **BELLO**: | Ife mi. (**KISSES**) Bawo ni? Se owa pa? |
| 7. | **ABOKEDE**: | Mo wa o. Wole. |
| 8. | **SFX**: | **<u>DOOR CLOSES</u>** |
| 9. | **BELLO**: | Aunty Wosilat nko? Ati Uncle Ajani? |
| 10. | **ABOKEDE**: | Aunty Wosilat ti lo soja. O sa mon pe won o fi oja won sere. Boda Ajani ti bere ise. Opelope daddy e |
| 11. | **BELLO**: | (**CHUCKLES**) Abokede, mo mon pe inu daddy dun lati se. (PAUSE) Ah, e ma ti lon ra nkan gann |
| 12. | **ABOKEDE**: | Beeni. Mo sare de oja leni. Wo awon nkan ti mo ra |
| 13. | **BELLO**: | O po o. Se owo ti mo fun e ka sha? |
| 14. | **ABOKEDE**: | Ah Bello, o to, o seku gann. Wo awon nkan to mo ra fun baami. Ti Tayo, ni eleyi, t'awon aburo mi niyi. Eyi ti mo ra fun awon ara ile wa ni Ibadan niyen |
| 15. | **BELLO**: | (**IN ADMIRATION**) Ta lo wa ni Ankara to fine bayi? |
| 16. | **ABOKEDE**: | (**SIGHS**) Aunty Iyabo ma ni. Olorun a je ki won kuku nife e |
| 17. | **BELLO**: | (**SURPRISED**) Ah ah? Ki wa ni aya e nja fun? Ninu gbogbo nkan ti o ra, eleyi gann lo fine ju. Mo de mo npe ohun na lo ma won ju. |

18. **ABOKEDE**: Bello, oo mo aunty Iyabo ni. Se ori, lati igba ti baami ti fe won lokan mi oti bale mon. Ko si nkan ti mo le se t'ole te aunty Iyabo lorun

19. **BELLO**: Abokede, kosi eni t'ole buuru to yen

20. **ABOKEDE**: (**CHUCKLES NERVOUSLY**) Bello, oo mon nkan ti mon so. Aunty iyabo buuru baje. Aya mi gan nja ati ri won ni Ibadan

21. **BELLO**: Well, ki ni won tun le se fun e? Oo si labe won mon now

22. **ABOKEDE**: Ah! Bello, aunty Iyabo man toju bo'le. Ko ni ya mi lenu ti won ba gbiyanju lati ba igbeyawo wa je

23. **BELLO**: Abokede, come on. Bawo ni won se fe se e? Gbogbo wa la ma wa nibe. Won o le se nkan kan

24. **ABOKEDE**: Bello, o mo npe aje-butter ni wo ni ti e. Nkan ti mon so o le ye e

25. **BELLO**: Wo'bi Abokede, ohun kohun oo baa sele, ma a wa pelu e. mi o ni je ki olo ri won fun ra e. ma wa pelu e sho gbo?

26. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 2**

**Ilorin! Ajani's apartment.**

27. **SFX:** <u>**DOOR OPENS AND CLOSES**</u>

28. **WOSILAT**: Eku ile o (I'm back o)

29. **AJANI**: Wossy mi, kaabo. (Welcome).

30. **WOSILAT**: Ajani mi, mo rin pe inu e dun gan leni o

31. **AJANI**: Emi ni mi oni yo si? Opelope aon anaa wa, emi ti di eni to nise niyen.

32. **WOSILAT**: Bawo ni ibise naa? Se oni ife e?

33. **AJANI**: Wossy mi, ki ni mi oni nife si? Se emi to je npe, owo ti mon gba ni ibise tuntun yi, ilopo meji loje si iyi ti mo ngba tele.

34. **WOSILAT**: Allahu akbar (God is great). Oluwa seun o. abokede ti ko ire bawa o. ah, inu mi dun gan pe mo mu wa lati Ibadan.

35. **AJANI**: Beeni o Wosilat. Ire nla l'Abokede ko wa o

36. **WOSILAT**: (**TEASINGLY**) Saa ma fi gbogbo owo e ta baba-ijebu tan

37. **AJANI**: (**CHUCKLES**) Baba ijebu ke, mi o nit a rara mo. Afi tin ba rip e awon number yen gba gann

38. **WOSILAT**: Oo mo nkan ti o nso o. Jo o Ajani, bii ti ose ri ise bayi nsinyin, bi ti a se ma kuro nibi yi lo ye ka ma ro o. awa na gbodo lo gba'le tiwa ni o

39. **AJANI**: Mo mo Wosilat. Emi na kan sere l'ekan yen ni.

40. **WOSILAT**: Ko ya je ere ni o. Enh enh! Ajani, se o mo nkan to sele loja leni?

41. **AJANI**: ki lo sele?

42. **WOSILAT**: Alaba ti ku!

43. **AJANI**: (**SURPRISED**) Alaba? Alaba wo?

44. **WOSILAT**: Alaba kan na. Alaba to ma nfun mi loja la win.

45. **AJANI**: Ah, Alaba yen? Ki lo pa a?

46. **WOSILAT**: Magun ni (A charm against cheating)

47. **AJANI**: Magun?

48. **WOSILAT**: Beeni o. a se Alaba nba iyawo oniyawo l'asepo. Oun o de mo npe oko iyen to fi magun si lara

49. **AJANI**: Ah! Omo 'kunrin yi de lopa ara e sha? Ki lo de ti iyawo ti e o te lorun?Afi iyawo oniyawo shaaa?

50. **WOSILAT**: Bi ti Alaba se ri niyen o. awon adelebo lohun ma n fe. O sa mo biti ose le emi na titi. O mo npe mo ni oko o. ntori mi o gba fun na ni ko se fun mi ni oja mo

51. **AJANI**: Oga o. Enh! oun ti oju e nwa, oun loju e tiri yen

52. **WOSILAT**: Abi? Sugbon sha o, eyin okunrin ngbiyanju o. aini itelorun lo man pa yin

53. **AJANI**: Ko n se gbogbo okunrin o. tani o ma ni iru iwo yi, to tun ma ma wo'ta? (**KISSES**) Ko le sele

54. **WOSILAT**: Hmm, Ajani. O tun ti bere o.

55. **AJANI**: Mo bere o. Sebi a tin se ifeto somo bibi, ko si iberu kan kan mo. (**KISSES CONTINUE**)

56. **WOSILAT**: Ko si wahala. Emi gan setan fun e. o mo npe bi ti a sen se ifeto somo bibi nsinyin, igba to ba wun mi ni mo ma loyun. Ajani mi, ifeto somo bibi yi daa gan o. o ti e je ki ife wa tun gbero si

57. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 3**

**Ibadan! Lukman's house. Evening!**

58. **SFX**: **<u>MANY EXCITED VOICES. SHOUTING HAPPILY. WORDS LIKE 'AUNTY ABOKEDE', 'EKAABO' (WELCOME), AWON TI ILORIN NKO (HOW ARE ILORIN FOLKS?) ARE HEARD</u>**

59. **ABOKEDE**: (**HAPPILY BUT HURRIEDLY**) Eku ile o. Mon bo, mon bo, ejen ko ko ri baami loke na

60. **SFX**: **<u>FEET SHUFFLES. DOOR OPENS AND CLOSES</u>**

61. **LUKMAN**: (**EXCLAIMS HAPPILY**) Abokede mi. kaa bo

62. **ABOKEDE**: Baami! Eku ojo meta

63. **LUKMAN**: ojo kan pelu! Awon ti Ilorin nko?

64. **ABOKEDE**: Won wa o, baami

65. **LUKMAN**: (**EXCITEDLY**) Omo mi Abokede. Maa bo, wa joko ti mi nbiyi

66. **ABOKEDE**: Ese baami

67. **LUKMAN**: Aunty e Wosilat nko? Ati Ajani?

68. **ABOKEDE**: Won wa. Awon naa o ni pe de

69. **LUKMAN**: Oko e nko? Mo ro npe e jo nbo ni

70. **ABOKEDE**: Aa jo de naa ni. Oun ko ko lo si hotel lati gbe eru e le na. Aa to de wa ki yin

71. **LUKMAN**: Ah. O ti wu mi kin rii o

72. **ABOKEDE**: Ko ni pe de baami. Ewo awon nkan ti mo ra fun yin

73. **LUKMAN**: Ah. Abokede. Eyii po o.

74. **ABOKEDE**: Mo ra eleyi fun Baba Wasiu.

75. **LUKMAN**: Ah, Baba Wasiu na ri gba

76. **ABOKEDE**: (**CHUCKLES**) Beeni o, baami. Ti Tayo niyi, awon aburo mi lo ni eleyi. Nma fun awon ara adugbo ni eleyi. Ma fun gbogbo to baya. E bami fun aunty iyabo ni eleyi

77. **LUKMAN**: (**SURPRISED**) ki lo de ti iwo ole fun funra e?

78. **ABOKEDE**: Ah baami, eyin na sa mo aunty Iyabo. Won le ma binu bee yen

79. **LUKMAN**: Binu npe kini? Pe o ra nkan wa fun?

80. **ABOKEDE**: Baami, e de nsor bi npe e o mo aunty Iyabo. E mo npe won o nife mi kobo

81. **LUKMAN**: (**SIGHS DEEPLY**) hmm. Abokede, inu re o dun ni gbogbo igba ti o wa nibi ki oto lo si Ilorin abi?

82. **ABOKEDE**: Baami, hmm, oju mi ri mabo. Sugbon, oun gbogbo nsise papo fun rere na ni

83. **LUKMAN**: Hmm

84. **ABOKEDE**: Looto ni o baami. Ti mba lo si Ilorin, emi na o ni di eni ti o nlo si university. Mi o de ni pade Bello

85. **LUKMAN**: Allahu akbar! Sugbon se oro omokunri yi daa e loju sha?

86. **ABOKEDE**: (**INCREDULOUSLY**) Bello?

87. **LUKMAN**: Enh. Se o feran e denu denu? Abi nitori owo e lose fe fe.

88. **ABOKEDE**: Baami, o ye ke mo mi ju beeyen lo. Mo nife Bello gan o. oun na de ntoju mi. baami, mi o fe Bello nitori owo o. mo ni fe denu denu ni

89. **LUKMAN**: Iwo to de sese wo ilewe giga. Se oko e ma je ko pari eko e bayi

90. **ABOKEDE**: (**CHUCKLES**) Baami, nitori e o tii mo Bello dada ni o. Bello o ti e nigba ti nba lo si school. Nitori e na ni emi ati Bello se lo se ifeto

so mo bibi, kin ma bale loyun afi igba ti nba setan lati beere sin bi'mo

91. **LUKMAN**: Ah oda o. eyin omo ode oni ti e gbon gan. E e kin gba igbakugba laye. (**PAUSE**, **THEN SADLY**) o ko dun mi ni npe iya o si laye lati ri omo rere ti o ti da

92. **ABOKEDE**: Baami, mo mo npe iya mi now mi lati orun. Mo de mo npeinu won dun simi

93. **LUKMAN**: (**IN ADMIRATION**) Abokede, omo mi, inu mi dun loni yi gan o. l'aduru gbogbo ohun ti o ti la koja, o tun se rere. Abokede, olorun a tubo ma wo e funmi

94. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 4**

**Ibadan! Lukman's house.**

95. **SFX**: <u>DOOR OPENS AND CLOSES</u>

96. **IYABO**: (**SURPRISED**) Ah ah? Bello. Ki lo de ti won da fi wo nikan le sibi? Ibo ni gbogbo won wa?

97. **BELLO**: Ah aunty Iyabo, daddy Abokede ti lo si moshalashi. Won ni awon oni oe de

98. **IYABO**: Enh enh? Abokede nko? Oun na de da fi e sile nibi?

99. **BELLO**: Oh o sese kuro nibi ni. O ni oun fe sare lo ki eyan kan ni sale. Lami abi ki lo ti pe oruko e

100. **IYABO**: (**MUMBLES**) Hmm. Iyen ku di e kaato o. bawo ni Abokede mase fi oko afesona e sile, to wan rin rin are kiri. (**CLAPS HER HANDS**) oga o.

101. **BELLO**: (**CHUCKLES**) Aunty Iyabo, iyen okin se wahala. O so fun mi koto lo, mo de gbaa laye. Iyen oto, e de ku alejo wa o. ounje yin ye dun gann

102. **IYABO**: (**EFFUSIVELY**) Enh enh Bello, oti e ni oro kan ti mo fe ba e so.

103. **BELLO**: (**POLITELY**) Enh enh? Se ko si o aunty Iyabo?

104. **IYABO**: (**BLUNTLY**) Bello, oo le fe Abokede o

105. **BELLO**: ko ye mi aunty Iyabo. Ki le mean by that?

106. **IYABO**: Oda. Eni beere oro, lo fe idi e gbo

107. **BELLO**: Mon gbo yin, aunty!

108. **IYABO**: (**WITH SATISFACTION**) Wo bi Bello, that Abokede that you think you want to marry, enh? She is a cursed childAbokede ti o ni ofe fe yen, omo eegun kan ma ni?

109. **BELLO**: Eegun? Enh enh?

110. **IYABO**: Beeni o Bello. Ati igba ti won ti bii ni egun tin baja. Abokede lo pa iya re o. gege bi ti won se bii na ni won da baba e duro ni Railway ti won tin sise

111. **BELLO**: Hmmm

112. **IYABO**: Omo yen o laanu rara. Se oti e ri Lami t'oni oun fe lo ki ni sale yen, oku di e ki Abokede paa danu

113. **BELLO**: Pa a? bi ti bawo?

114. **IYABO**: Ah! Ko so yen fun e abi? Je ki emi so fun e. Se ori, Abokede ati Lami, ore ni won pe ara won o. igba ti omobirin yen nrobi, Abokede tan pe oun a baa pe oko e, sugbon ni se lo salo, to fi Lami le nibi to tin robi. Olorun lo yo omobirin yen o

115. **BELLO**: Aunty, ewo...

116. **IYABO**: (**INTERRUPTS**) Ko tan sibe o Bello. Abokede ti iwo ni o fe fe yi, ole paburata ni. Ko si eni to jale to. mo de mo npe ko ni'fe e kobo. Owo owo e lo fe gba.

117. **BELLO**: (**CALMLY**) Aunty Iyabo, ese fun gbogbo oro ti e so sugbon ko wa necessary rara. Se ri Abokede ti e nsoro e yen, mi o ti ri eni to ni iwa to.

118. **IYABO**: Ah! O n tan e je ni. Bello, ma…

119. **BELLO**: (**INTERRUPTS FIRMLY BUT POLITELY**) Ewo ibi madam. Eyi ti e so yen oti to ge. Ko si eyi to kan mi o, ti e bar o npe Abokede da abi ko da. Sugbon e ma ever so oro e fun mi mo

120. **IYABO**: (**SHOCKED**) Bello. Se emi lon bawi beeyen?

121. **BELLO**: Mi o ri elomi ni biyi. Ewo bi aunty, se eri gbogbo nkan ti e so, ma se bi npe mi o gbo. But ejo, ema je ki iru tun sele mo

122. **IYABO**: Ki lon se iwo omo ana yi? Mon ba e soro aiye e …

123. **BELLO**: Ese o. sugbon, ejo e respect ara yin next time. alejo ni mi ni ile yi, ejo ema je kin ri yin fin.

124. **IYABO**: (**ANGRILY**) Enh enh? Iyen emi na? bello! Waa gba! Sebi emi ni iwo lanu soro si beeyen? Waa gba!

125. **MUSIC**: **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**